


Láti ọwọ́ Ààrẹ Thomas S. Monson

# Àwọn Ìbùkún ti Tẹ́mpìlì

*Bí a ṣe ńlọ sí tẹ́mpìlì, oníruru ọ̀nà ti ẹ̀mí àti ìmọ̀ara àláfíà kan ni ó lè wá sọ́dọ̀ wá.*

Ẹ̀yin arákùnrin àti arábìnrin mi ọ̀wọ́n, mo fi ìmoore hàn fún wíwà pẹ̀lú yín ní ààrọ̀ Àjínde ẹlẹ́wà yí nígbàtí èrò wa nyí sọ́dọ̀ Olùgbàlà aráyé. Mo nàwọ́ ìfẹ́ àti ìkínni mi sí ìkọ̀ọ̀kan yín mo sì gbàdúrà pé kí Bàbá Ọ̀run fi ìmísí sí àwọn ọ̀rọ̀ mi.

Ìpàdé yí ló jẹ́ ọdún kéje láti ìgbà tí a ti ṣe ìmúdúró fún mi gẹ́gẹ́bí Ààrẹ Ìjọ. Wọ́n jẹ́ àwọn ọdún iṣẹ́ àṣekára, kìí ṣe tó kún fún àwọn ìpèníjà díẹ̀ níkan ṣùgbọ́n pẹ̀lú àwọn àìlónkà ìbùkún bákannáà. Nínú àwọn ìbùkún tí mo gbádùn àti èyí tó sì jẹ́ mímọ́ jùlọ ni ànfàní tí mo ní láti ṣe ìyasímímọ́ àti láti tún àwọn tẹ́mpìlì yàsímímọ́.

Láìpẹ́ yí gan an, ní oṣù kọ̀kànlá tó kọjá ó jẹ́ ànfàní mi láti ya Tẹ́mpìlì ẹlẹ́wà tuntun ti Phoenix Arizona sí mímọ́. Ààrẹ Dieter F. Uchtdorf, Alàgbà Dalling H. Oaks, Alàgbà Richard J. Maynes, Alàgbà Lynn G. Robbins, àti Alàgbà Kent F. Richards ni wọ́n darapọ̀ mọ́ mi. Ní ìrọ̀lẹ́ tó ṣaájú ìyàsímímọ́ náà, wọ́n ṣe ayẹyẹ ọ̀làjú ìyanilẹ́nu kan níbití ẹgbẹ̀rún mẹ́rin àwọn ọ̀dọ́ wa láti ẹ̀kùn tẹ́mpìlì ti ṣeré dáradára. A ya tẹ́mpìlì náà sí mímọ́ lọ́jọ́ tó tẹ̀le nínú àwọn abala mímọ́ àti ònímísí mẹ́ta.

Àwọn ilé tẹ́mpìlì jẹ́ ìfihàn tó mọ́ kedere nípa ìdàgbàsókè Ìjọ. Lọ́wọ́lọ́wọ́ a ní àwọn tẹ́mpìlì mẹ́rin lé lógóje tó wà ní lílò káàkiri àgbáyé, pẹ̀lú márún tí à ntúnṣe lọ́wọ́ àti mẹ́tàlá tó wá lábẹ́ kíkọ́ lọ́wọ́. Ní àfikún, àwọn tẹ́mpìlì mẹ́tàlá tí a ti kéde tẹ́lẹ̀ ti wa ní onírurú ìmúrasílẹ̀ ìgbésẹ̀ ṣíwájú ìgbà tí kíkọ́ yíò bẹ̀rẹ̀. Ní ọdún yí a ngbèrò láti tún ya àwọn tẹ́mpìlì méjì sí mímọ́ àti pé kí a sì ya àwọn tẹ́mpìlì tuntun márún sí mímọ́ èyí tí a ti fi sípò ìparí.

Fún ọdún méjì tó kọjá, bí a ṣe nfi ìgbìyànjú wa lórí píparí àwọn tẹ́mpìlì tí a ti kéde tẹ́lẹ̀, a ti ní àwọn ètò ní ìdádúró fún àfikún àwọn tẹ́mpìlì kankan. Ní ààrọ̀ yí, bí ó ti wù kí ó rí, inú mi dùn láti kéde àwọn tẹ́mpìlì tuntun mẹ́ta èyí tí a ó kọ́ ní àwọn ibí wọ̀nyí: Abidjan, Ivory Coast; Port-au-Prince, Haiti; àti Bangkok, Thailand. Àwọn ìbùkún àràmàdà ni ó jẹ́ tó wà nísúra fún àwọn ọmọ ìjọ olódodo ní àwọn agbègbè wọ̀nyí àti pé nítòótọ́, níbikíbi tí àwọn tẹ́mpìlì wà káàkiri àgbáyé.

Ètò ti pípinnu àìní àti wíwá àwọn ibùjókó fún àfikún tẹ́mpìlì ṣì nlọ lọ́wọ́, nítorí a nífẹ́ pé kí ó lè ṣeéṣe fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọmọ ìjọ láti ní ànfàní láti lọ sí tẹ́mpìlì láìsí àwọn ìrúbọ ńlá ti àkokò àti àwọn ohun èlò. Gẹ́gẹ́bí a ti ṣe tẹ́lẹ̀ rí, a ó máa sọ fún un yín bí a ó ṣe máa pinnu ohun tí a ó ṣe ní ìkàsí yí.

Bí mo ṣe nronú nípa àwọn tẹ́mpìlì, àwọn èrò mi nyípadà sí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìbùkún tí à ngbà nínú rẹ̀. Bí a ṣe nwọlé láti ẹnu ọ̀nà tẹ́mpìlì, à nfi àwọn ìdíwọ́ àti ìdàmú ayé wa sílẹ̀ sẹ́hìn. Nínú ilé Ọlọ́run mímọ́ yí, à nrí ẹwà àti ètò. Ìsinmi wà fún àwọn ẹ̀mí wa àti ààyè kúrò nínú àníyàn ti ayé wa.

Bí a ṣe nlọ sí tẹ́mpìlì, ìwọ̀n ti ẹ̀mí lè wá sọ́dọ̀ wa àti ìmọ̀ara àláfíà kan èyí tí yíò tóbi ju ìmọ̀ara míràn èyí tí ó lè wá sínú ọkàn ọmọ ènìyàn. A ó di àwọn ọ̀rọ̀ Olùgbàlà tí ó jẹ́ ìtumọ̀ otítọ́ gan mú nígbàtí Ó sọ pé: "Àláfíà ni mo fi sílẹ̀ fún yín, àláfíà mi ni mo fún yín. . . . Ẹ máṣe jẹ́ kí ọkàn yín dàrú, ẹ má sì ṣe jẹ́ kí ó wárìrì."[1]

Irú àláfíà náà lè wọ èyíkéyí ọkàn lọ—àwọn ọkàn tí ó dàmú, àwọn ọkàn tí a gbé àjàgà lé pẹ̀lú ìkẹdùn, àwọn ọkàn tó ní ìmọ̀ara ìdàrúdàpọ̀, àwọn ọkàn tó nbẹ̀bẹ̀ fún ìrànlọ́wọ́.

Mó kẹ́kọ́ láìpẹ́ yìí nípa ọ̀dọ́mọkùnrin kan tó lọ sí tẹ́mpìlì pẹ̀lú ọkàn kan

tó ńbẹ̀bẹ̀ fún ìrànlọ́wọ́. Ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ oṣù ṣíwájú ó ti gba ìpè láti sìn ní míṣọ̀n kan ní Àríwá Amẹ́ríkà. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, wọ́n dá ìwé ìkọjá rẹ̀ dúró fún ìgbà pípẹ́ tí ó fi jẹ́ pé wọ́n fi tún ìyànsílẹ̀ rẹ̀ sí míṣọ̀n kan ní United States ṣe. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ó ní ìdálára pé òun kò lè sìn ní agbègbè tí a kọ́kọ́ pè é sí, síbẹ̀síbẹ̀ ó ṣiṣẹ́ àṣekára níbi ìyànsílẹ̀ rẹ̀ tuntun, ó pinnu láti sìn dé ibi tí ipá rẹ̀ lè gbe dé. Ó di ẹnití amúlọ́kàn kúrò nínú iṣẹ́ ìránṣẹ́ náà, bákannáà, nítorí ti àwọn ìrírí òfò tí ó ti ní pẹ̀lú àwọn ìránṣẹ́ ìhìnrere tí ó dàbíí pé wọ́n ní ìfẹ́ nínú ìgbádùn jù ṣíṣe àbápín ìhìnrere lọ.

Ní àwọn oṣù kúkúrú díẹ̀ lẹ́hìn náà ọ̀dọ́mọkùnrin yí jìyà ìpèníjà ìlera tó le gidi èyí tó mu ní àrùn ẹ̀gbà tó fi di aláàbọ̀ ara, àti pé nítorí bẹ́ẹ̀ a dá a padà sílé kí ó ní ààyè láti lọ tọ́jú ara rẹ̀.

Ní àwọn òṣù díẹ̀ lẹ́hìnnáà ọ̀dọ́mọkùnrin náà ti rì ìwòsàn tán pátápátá, àti pé àrùn ẹ̀gbà rẹ̀ ti lọ. Wọ́n sọ fún pé òun yíò lè sìn gẹ́gẹ́bí ìránṣẹ́ ìhìnrere kan lẹ́ẹ̀kan si, ìbùkún kan fún èyítí ó ti ngbàdúrà fún lójoojúmọ́. Ìròhìn ìdálára kanṣoṣo tó ní ni wípé òun yíò padà lọ sí míṣọ̀n kannáà èyí tí ó ti kúrò, níbití ó rò wípé àwọn ìwà àti ìhùwàsí ìránṣẹ́ ìhìnrere ti dínkù jú bí ó ti yẹ lọ.

Ó ti wá sí tẹ́mpìlì láti wá ìtùnú rí àti ìfẹsẹ̀múlẹ̀ kan pé òun yíò ní ìrírí rere kan gẹ́gẹ́bí ìránṣẹ́ ìhìnrere kan. Àwọn òbí rẹ̀ ti gbàdúrà pé wíwá sí tẹ́mpìlì yí yíò pèsè ìrànlọ́wọ́ tí ọmọkùnrin wọn nílò.

Bí ọ̀dọ́mọkùnrin náà ṣe wọlé sínú yàrá sẹ̀lẹ́stíà lẹ́hìn abala náà, ó jókó sínú àga kan ó sì bẹ̀rẹ̀sí ngbàdúrà fún ìtọ́sọ́nà látọ̀dọ̀ Bàbá rẹ̀ Ọ̀run.

Ẹlòmíràn tó wọlé sínú yàrá sẹ̀lẹ́stíà náà ní kété lẹ́hìn náà ni ọ̀dọ́mọkùnrin tí orúkọ rẹ̀ njẹ́ Lándon. Bí ó ṣe nrìn lọ sínú yàrá, lọ́gan ojú rẹ̀ lọ sọ́dọ̀ ọ̀dọ́mọkùnrin tó jókó lórí àgà, tó pajúdé tó hàn pé ó ngbàdúrà. Landon gba ìṣílétí tí kò láṣìṣe kan pé òun níláti sọ̀rọ̀ pẹ̀lú ọ̀dọ́mọkùnrin náà. Lílọ́ra láti di lọ́wọ́, bákannáà, ó gbèrò láti dúró. Lẹ́hìn tí àwọn ìṣẹ́jú díẹ̀ ti kọjá lọ, ọ̀dọ́mọkùnrin náà ṣì ngbàdúrà. Landon mọ̀ pé òun kò lè ti ìṣílétí náà síwájú sìí mọ rárá. Ó dé ọ̀dọ̀ ọ̀dọ́mọkùnrin náà ó sì fọwọ́kàn èjìká rẹ̀ jẹ́jẹ́. Ọ̀dọ́mọkùnrin náà la ojú rẹ̀, ó tagìrì pé wọ́n yọ òun lẹ́nu. Landon fi pẹ̀lẹ́pẹ̀lẹ́ sọ pé, "Mo ní ìmọ̀ara ìtẹ̀mọ́ra pé mo níláti sọ̀rọ̀ pẹ̀lú rẹ, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé èmi kò mọ ìdí rẹ dájúdájú."

Bí wọ́n ṣe bẹ̀rẹ̀ sí ńsọ̀rọ̀, ọ̀dọ́mọkùnrin náà tú ọkàn rẹ̀ jáde sí Landon, ó ṣàlàyé àwọn ipò rẹ̀, ní ìparí pẹ̀lú ìfẹ́ rẹ̀ láti gba àwọn ìtùnú àti ìgbìyàjú nípa míṣọ̀n rẹ̀. Landon, ẹnití ó ṣẹ̀ṣẹ̀ padà láti àṣeyege míṣọ̀n kan ní ọdún kan péré sẹ́hìn, sọ nípa àwọn ìrírí míṣọ̀n ti ara rẹ̀, àwọn ìpèníjà àti àwọn àníyàn tí ó ti dojúkọ́ọ́, ìrú ọ̀nà èyí tí óun ti yí sí sọ́dọ̀ Olúwa fún ìrànlọ́wọ́, àti àwọn ìbùkún tí òun ti gbà. Àwọn ọ̀rọ̀ rẹ̀ ntuni nínú ó sì tún dánilójú si, àti pé ìwúrí rẹ̀ fún míṣọ̀n rẹ̀ jẹ́ ríranni. Ní òpin, gẹ́gẹ́bí àwọn ìbẹ̀rù ọ̀dọ́mọ̀kùnrin náà ṣe rọlẹ̀, ìmọ̀ara àlàfíà wá sọ́dọ̀ rẹ̀. Ó ní ìmọ̀ara ìmoore ìjìnlẹ̀ bí ó ṣe mọ̀ pé àdúrà òun ti gbà.

Àwọn ọ̀dọ́mọkùnrin méjèjì náà gbàdúrà papọ̀, nígbànáà Landon múra láti lọ, nínì ìnú dídùn pé òun ti fetísílẹ̀ sí ìmísí èyítí ó ti wá sọ́dọ̀ rẹ̀. Bí ó ṣe dide dúró láti lọ, ọ̀dọ́mọkùnrin náà bi Landon pé, "Níbo ni ìwọ ti ṣe iṣẹ́ ìránṣẹ́ rẹ?" Títí di àsìkò yí, kò sí ìkọ̀ọ̀kan lára wọn tí ó ti sọ orúkọ míṣọ̀n tí ó ti sìn sí fún ara wọn. Nígbàtí Lándon fèsì pẹ̀lú orúkọ míṣọ̀n rẹ̀, omijé jáde ní ojú ọ̀dọ́mọkùnrin náà. Landon ti sìn ní míṣọ̀n náà gan èyí tí ọ̀dọ́mọkùnrin náà npadà lọ!

Nínú lẹ́tà kan sí mi láìpẹ́, Landon ṣe àbápín àwọn ọ̀rọ̀ ìyapa ọ̀dọ́mọkùnrin náà pẹ̀lú mi: "Mo ní ìgbàgbọ́ pé Bàbá Ọ̀run yíò bùkún mi, ṣùgbọ́n èmi kò ti lérò pé Òun yíò rán ẹnìkan tí ó ti sìn rí ni míṣọ̀n ara mi láti ràn mí lọ́wọ́. Mo mọ̀ báyìí pé gbogbo rẹ̀ yíò dára."[2] Àdúrà ìrẹ̀lẹ̀ ti ọkàn òdodo ni a ti gbọ́ tí a sì ti dáhùn.

Ẹ̀yin arákùnrin àti arábìnrin mi, nínú ayé wa a ó ní àwọn àdánwò; a ó ní àwọn ìdánwò àti ìpèníjà. Bí a ṣe nlọ sí tẹ́mpìlì, bí a ṣe nrántí àwọn májẹ̀mú tí à ṣe níbẹ̀, a ó lè borí àwọn àdánwò wọnnì dáradára à ó sì lè gba àwọn ìdánwò wa mọ́ra. Nínú tẹ̀mpìlì a lè rí àlàfíà.

Àwọn ìbùkún tẹ́mpìlì kò níye. Ìkan fún èyítí mo fi ìmoore hàn fún jù lójoojúmọ́ ayé mi ni èyítí olólùfẹ́ aya mi, Frances, àti èmi gbà bí a ṣe kúnlẹ̀ ní pẹ́pẹ́ mímọ́ kan tí a sì dá àwọn májẹ̀mú tí ó so wá papọ̀ fún gbogbo ayé àìlópin. Kò sí ìbùkún tí ó níyì sí mi jù àlàfíà àti ìtùnú tí mo gbà láti inú òye tí mo ní pé òun àti èmi yíò wà papọ̀ lẹ́ẹ̀kansi.

Njẹ́ kí Bàbá wa Ọ̀run bùkún wa kí a lè ní ẹ̀mí ìjọsìn ti tẹ́mpìlì, kí a lè ṣe ìgbọ́ran sí àwọn òfin Rẹ̀, àti pé kí a lè fi pẹ̀lẹ́pẹ̀lẹ́ tẹ̀lé àwọn ìgbésẹ̀ Olúwa àti Olùgbàlà wa, Jésù Krístì. Mo jẹ́rí pé Òun ni Olùràpada wa. Òun ni Ọmọ Ọlọ́run. Òun ni ẹni tí ó jáde wá láti inú ìsà òkú ní ààrọ̀ Àjìnde àkọ́kọ́, tó mú ẹ̀bùn ìyè àìnípẹ̀kun fún gbogbo àwọn ọmọ Ọlọ́run wá pẹ̀lú Rẹ̀. Ní ọjọ́ ẹlẹ́wà yí, bí a ṣe nṣàyẹyẹ ìṣẹ̀lẹ̀ pàtàkì náà, njẹ́ kí a gbàdúrà fífi ìmoore hàn nítorí àwọn ẹ̀bùn nlá àti ìyanu Rẹ̀ sí wa. Kí èyí lè jẹ́ bẹ́ẹ̀, ni mo firẹ̀lẹ̀ gbàdúrà ní orúkọ mímọ́ Rẹ̀, àmín.

**ÀWỌN ÀKỌSÍLẸ̀ RÁNPẸ́**


1. Jòhánù 14:27.
2. Ìfiwéṣọwọ́ ránṣẹ́ ní ìkawọ́ Thomas S. Monson

# Àwọn Ìkẹ́kọ́ fún Ìgbà Tiwa

Láti Oṣù Kárún Ọdún 2015 sí Oṣù Kẹ́wá Ọdún 2015, Àwọn Ẹ̀kọ́ Oyè Àlùfáà Mẹ́lkìsédékì àti Ẹgbẹ́ Ìrànlọ́wọ́ ní Ọjọọjọ́ Ìsinmi Kẹ́rín ni a gbọ́dọ̀ pèsè láti inú àwọn ìsọ̀rọ̀ kan tàbí jùbẹ́ẹ̀ lọ nínú ìpàdé gbogboògbò Oṣù Kẹ́rin Ọdún 2015. Ní Oṣù Kẹ́wá, a lè yan àwọn ìsọ̀rọ̀ láti inú bóyá ìpàdé gbogboògbò Oṣù Kẹ́rin tàbí Oṣù Kẹ́wá. Àwọn Ààrẹ Èèkàn àti Ẹ̀kùn gbọ́dọ̀ yan àwọn ìsọ̀rọ̀ èyí tí wọn yíò lò ní àwọn agbègbè wọn, tàbí wọ́n lè fún àwọn bíṣọ́ọ̀pù àti àwọn ààrẹ ẹ̀yà ní ojúṣe yí.

Àwọn ọ̀rọ̀ yí wà ní oríṣiríṣi àwọn èdè ní conference.lds.org.

© 2015 láti ọwọ́ Intellectual Reserve, Inc. All rights reserved. Tí a tẹ̀ ní USA. Àṣẹ Gẹ̀ẹ́sì: 6/14 Àṣẹ Ìyírọ̀padà: 6/14 Ìyírọ̀padà ti *First Presidency Message, May 2015.* Yoruba. 12585 779



**Láti Ọwọ́ Ààrẹ Dieter F. Uchtdorf**
Olùdámọ̀ràn Ìkejì nínú Àjọ Ààrẹ Ìkínní

# Ẹ̀bùn Oore Ọ̀fẹ́

*Lóní àti títí láé oore ọ̀fẹ́ wà fún gbogbo àwọn tí ó ní ìrora ọkàn àti àwọn tí wọ́n ní ẹ̀mí ìròbìnújẹ́.*

Ní Ọjọ́ Ìsinmi Àjíǹde à nṣàjọyọ̀ ìṣẹ̀lẹ̀ ínú ìwé ìtàn àgbáyé ti a tii dúró dè tipẹ́tipẹ́ tí ó sì jẹ́ ológo.

Ó jẹ́ ọjọ́ tí ó yí gbogbo nkan padà.

Ní ọjọ́ náà, ìgbésí ayé mi yípadà.

Ìgbésí ayé tìrẹ yípadà.

Àyànmọ́ gbogbo àwọn ọmọ Ọlọ́run yípadà.

Ní ọjọ́ alábùkún náà, Olùgbàlà gbogbo aráyé, ẹnití ó gbé ìdé ẹ̀ṣẹ̀ àti ikú sórí ara Rẹ̀, èyítí ó mú wá ní ìgbèkùn, já àwọn ìdè wọ̀nnì Ó sì tú wa sílẹ̀.

Nítorí ìrúbọ àyànfẹ́ Olùràpadà wa, ikú kò nípa mọ́, isà òkú kò níṣẹ́gun kankan,[1] Sátánì kò ní agbára pípẹ́ mọ́, àti pé a jẹ́ "ọmọbíbí . . . lẹ́ẹ̀kansi sí ìrètí ààyè nípa *àjíǹde* ti Jésù Krístì."[2]

Nítòótọ́, Àpóstélì Páùlù yege nígbàtí ó sọ pé a lè "tu ara wa nínú pẹ̀lú àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí."[3]

#### Oore Ọ̀fẹ́ Ọlọ́run

À nfìgbàkugbà sọ̀rọ̀ Ètùtù Olùgbàlà—àti pé bẹ́ẹ̀ ni lóòtọ́!

Nínú àwọn ọ̀rọ̀ Jákọ́bù, "Kínìdí tí a kò fi ní sọ̀rọ̀ ètùtù ti Krístì, kí a sì dé ìmọ̀ pípé nípa rẹ̀?"[4] Ṣùgbọ́n bí a bá ṣe "nsọ̀rọ̀ ti Krístì, . . . yayọ̀ nínú Krístì, . . . wàásù nipa Krístì, [àti] sàsọtẹ́lẹ̀ nípa Krístì"[5] ní gbogbo ànfàní, a kò gbọ́dọ̀ jù òye ti ọ̀wọ̀ àti ìmoore tó jinlẹ̀ fún ìrúbọ ayérayé ti Ọmọ Ọlọ́run sọnù

Ètùtù Olùgbàlà kò lè di ohun tó wọ́pọ̀ nínú ìkẹ́kọ́ wa, nínú ìbásọ̀rọ̀ wa, tàbí nínú ọkàn wa. Ó jẹ́ mímọ́ àti àìléèrí, nítorí nípa "ìrúbọ tó kẹ́hìn àti ńlá" yìí ni Jésù Krístì náà mú "ìgblà wá fún gbogbo àwọn wọ̀nnì tí yíò gbàgbọ́ nínú orúkọ rẹ̀."[6]

Ó yà mí lẹ́nu láti rò wípé Ọmọ Ọlọ́run yíò rẹ ara rẹ̀ sílẹ̀ láti gbà wá là, gẹ́gẹ́bí àlàìpé, àlàìmọ́, ẹni tí ó lè ṣìṣe, àti aláìmoore ti a máa njẹ́ nìgbàkugbà. Mo ti tiraka láti lóye Ètùtù Olùgbàlà pẹ̀lú iyè mi tó lópin, àti pé àlàyé kanṣoṣo tí mo lè mú wá ni èyí: Ọlọ́run nífẹ́ wa jinlẹ̀jinlẹ̀, ní pípé àti títí dópin. Èmi kò lè bẹ̀rẹ̀ sí ṣíró "ìbú, gígùn, jíjìn, àti gíga . . . [ti] ìfẹ́ Krístì."[7]

Ìfihàn ìfẹ́ kan tí ó lágbára ni ohun tí ìwé mímọ́ máa nfìgbàkugbà pè ní *oore ọ̀fẹ́ Ọlọ́run*—àtìlẹ́hìn ti ọ̀run àti ẹ̀bùn agbára nípasẹ̀ èyítí a fi ndàgbà sí látinú àbùkù àti lílópin ẹ̀dá tí a jẹ́ báyìí sínú ìgbéga ẹ̀dá ti "òtítọ́ àti ìmọ́lẹ̀, títí [a ó fi] ṣògo nínú òtítọ́ àti pé tí a ó sì [mọ̀] ohun gbogbo."[8]

Ó jẹ́ ohun ìyanu jùlọ, oore ọ̀fẹ́ Ọlọ́run yí. Síbẹ̀síbẹ̀ a kìí fìgbàkugbà ní òye rẹ̀.[9] Àní bẹ́ẹ̀ni, a gbọ́dọ̀ mọ̀ nípa oore ọ̀fẹ́ Ọlọ́run tí a bá gbìrò láti jogún nkan tí a ti pèsè fún wa nínú ìjọba ayérayé Rẹ̀.

Sí òpin èyí mo fẹ́ láti sọ̀rọ̀ nípa oore ọ̀fẹ́. Ní pàtàkì, ìkínní, bí oore ọ̀fẹ́ ṣe *ńṣí àwọn ilẹ̀kùn ọ̀run* àti, ìkejì, bí ó ṣe *nṣí àwọn fèrèsé ọ̀run*.

#### *Ìkínní: Oore Ọ̀fẹ́ Nṣí Àwọn Ilẹ̀kun Ọ̀run*

Nítorí gbogbo wa ni a ti "ṣẹ̀, tí a sì ti kùnà ògo Ọlọ́run"[10] àti nítorí pé "ohun àìmọ́ kankan kò lè wọ ìjọba Ọlọ́run,"[11] gbogbo wa ni a kò yẹ láti padà sí ìwájú Ọlọ́run.

Àní tí a bá níláti sin Ọlọ́run pẹ̀lú gbogbo ẹ̀mí wa, kò tó, nítorí a ó ṣì jẹ́ "aláìlérè ìránṣẹ́ síbẹ̀."[12] A kò lè rí ọ̀nà gbà lọ̀ sí ọ̀run; àwọn ìbèèrè fún ìdálare dúró bí ìdènà, èyí tí a kò ní agbára láti borí fúnra wa.

Ṣùgbọ́n gbogbo rẹ̀ kò tíì sọnu.

Oore ọ̀fẹ́ Ọlọ́run ni ìrètí nlá áti àìlópin wa.

Nípa ìrúbọ Jésù Krístì, ètò àánú nṣípẹ̀ fún ìbèèrè ìdálare[13] "ó sì [nmú] ọ̀nà tí àwọn ènìyàn fi lè ní ìgbàgbọ́ sí ìrònúpìwàdà wá sí wọn."[14]

Àwọn ẹ̀ṣẹ̀ wa, bí ó tilẹ̀ jẹ́pé ó dàbí aṣọ òdòdó, lè di funfun bí ẹ̀gbọ̀n òjò dídì.[15] Nítorí Olùgbàlà olólùfẹ́ wa "fi ara rẹ̀ ṣe ìràpadà fún gbogbo ènìyàn,"[16] ojú ọ̀nà àbáwọlé sínú ìjọba àìlópin Rẹ̀ ní a ti pèsè fún wa.[17]

Ẹnu ilẹ̀kùn náà ti Ṣí!

Ṣùgbọ́n oore ọ̀fẹ́ Ọlọ́run kò dáwapadà sí ipò àìlẹ́bi wa tẹ́lẹ̀ lásán. Tí ìgbàlà bá túmọ̀ sí pé a nu àwọn àṣìṣe àti ẹ̀ṣẹ̀ wa kúrò nìkan, nígbànáà ìgbàlà—bí ó ṣe yanilẹ́nu tó—kò mú àwọn ìgbìrò Bábá fún wa wá sí ìmúṣẹ. Ohun tó fẹ́ jù bẹ́ẹ̀ lọ: Ó nfẹ́ kí àwọn ọmọkùnrin àti àwọn ọmọbìnrin Rẹ̀ dàbíí Tirẹ̀.

Pẹ̀lú ẹ̀bùn oore ọ̀fẹ́ Ọlọ́run, ipá

ọ̀nà ti ọmọléhìn kò ní darí pada sẹ́hìn; ó ndarí sókè ni.

Ó ndarí sí òkè tí a lè fi agbára káká lóye! Ó ńdarí sí ìgbéga ní ìjọba sẹ̀lẹ́stíà ti Bàbá wa Ọ̀run, níbi tí àwa, àti àwọn tí wọ́n fẹ́ràn, ti yí wa ká, gba "ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ rẹ̀, àti ògo rẹ̀ ."[18] Ohun gbogbo jẹ́ tiwa, Àti pé a jẹ́ ti Krístì.[19] Nítòótọ́, Gbogbo ohun tí Bàbá ní ni ó ti fi fún wa.[20]

Láti jogún ògo yí, a nílò ju ilẹ̀kùn ṣíṣí lọ: a gbọ́dọ̀ wọlé láti ẹnu ilẹ̀kùn pẹ̀lú ìfẹ́ ọkàn kan láti yípadà—ìyípadà kánmọ́kánmọ́ gidi tí àwọn ìwé mímọ́ ṣàpèjúwé rẹ̀ pé ó jẹ́ "àtúnbí; bẹ́ẹ̀ni, bíbí ti Ọlọ́run, ìyípadà kúrò ní ipò [ìgbéayé wa] àti ti ìṣubú, sí ipò òdodo, dídi íràpadà nipa ti Ọlọ́run, dídi àwọn ọmọkùnrin àti ọmọbìnrin rẹ̀."[21]

***Ìkejì: Oore Ọ̀fẹ́ Nṣí Àwọn Fèrésé Ọ̀run***

Ohun èlò míràn ti oore ọ̀fẹ́ Ọlọ́run ni ṣíṣí àwọn fèrèsé ọ̀run, nípa èyí tí Ọlọ́run nda àwọn ìbùkún agbára àti okun jáde, tí ó njẹ́ kí a le ṣe àṣeyege àwọn ohun tí ìbá kọjá ìnawọ́sí wa nígbàmíràn. Ó jẹ́ nípa àrà oore ọ̀fẹ́ Ọlọ́run pé àwọn ọmọ Rẹ̀ lè borí ìjì abẹ́ àti àgàbàgebè ti ẹlẹ́tàn, borí ẹ̀ṣẹ̀, kí a sì "di [pípé] nínú Krístì."[22]

Bí o tilẹ̀ jẹ́ pé gbogbo wa la ní àwọn àìlera, a lè borí wọn. Nítòótọ́ nípasẹ̀ oore ọ̀fẹ́ Ọlọ́run pé tí a bá rẹ ara wa sílẹ̀ tí a sì ní ìgbàgbọ́, àwọn ohun àìlera lè di alágbára.[23]

Ní gbogbo ayé wa, oore ọ̀fẹ́ Ọlọ́run nfi àwọn ìbùkún ti ayé yìí àti àwọn ẹ̀bùn ti ẹ̀mí tí ó nmú agbára wa gbòòrò lé wa lórí, tí ó sì nbu ọrọ̀ sí ayé wa. Oore ọ̀fẹ́ Rẹ̀ ntún wa ṣe. Oore ọ̀fẹ́ Rẹ̀ nrànwá lọ́wọ́ láti di dídára síi fúnra wa.

**Ta ló lè kún ojú òsùnwọ̀n?**

Nínú Bíbélì a kà nípa ìbẹ̀wò Krístì sí ilé Símónì tó jẹ́ Pharisee.

Ní gbangba, Símónì dàbí ẹni rere àti olóòtọ́ ọkùnrin. Ó nwo àwọn nkan tí òun gbọ́dọ̀ máa ṣe tí ó tò silẹ̀ ní ti ojúṣe ẹ̀sìn rẹ déédé: ó pa òfin mọ́, ó san ìdámẹ́wàá rẹ̀, ó pa Ọjọ́ Ìsinmi mọ́, ó ńgbàdúrà lójojúmọ́, ó sì ńlọ sí sínágọ́gù.

Ṣùgbọ́n nígbàtí Jésù wà pẹ̀lú Símónì, obìnrin kan súnmọ́ ọn, ó sì wẹ ẹsẹ̀ Olùgbàlà pẹ̀lú omijé rẹ̀, ó sì fi òróró dídára pa ẹsẹ̀ Rẹ̀.

Inú Símónì kò dùn pẹ̀lú àṣehàn ẹ̀sìn yí, nítorí ó mọ̀ pé obìnrin yí jẹ́ ẹlẹ́ṣẹ̀. Símónì rò pé bí Jésù kò bá mọ èyí, Òun kò gbọ́dọ̀ jẹ́ wòlíì tàbí Òun kì bá tí jẹ́ kí obìnrin náà fọwọ́ kan òun.

Wíwòye èrò rẹ̀, Jésù yípadà sí Símónì ó sì bií ní ìbèèrè kan. "Onígbèsè kan wà tí ó ní àwọn ajigbèsè méjì. ". . . Ìkan jẹ ẹ́ ní ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta owó idẹ, . . . èkejì sì jẹ ẹ́ ni ààdọ́ta.

"Àti pé nígbàtí àwọn [méjèèjì] kò sì ní owó tí wọn yíò san, ó dáríjì àwọn méjèèjì. Wí fún mi nígbànáà, nínú àwọn méjèèjì tani yíò fẹ́ran rẹ̀ jù?"

Símónì dáhùn wipe ẹnití ó dáríjì jù ni.

Nígbànáà Jésù kọni ní ẹ̀kọ́ ìjìnlẹ̀ kan: "Ìwọ rí obìnrin yí bí? . . . A dárí ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀, tó pọ̀, jìí; *nítorítí ó ní ìfẹ́ púpọ̀:* ẹnití a sì dárí díẹ̀ jì, òun náà ni ó ní ìfẹ́ díẹ̀."[24]

Èwo nínú àwọn ènìyàn méjì wọ̀nyí ni a dàbí rẹ̀ jù?

Ṣe a dàbí Símónì bí? Ṣe a nídánilójú àti ìtùnú nínú àwọn ìṣe rere wa, gbígbẹ́kẹ̀lé òdodo ara wa bí? Tàbí bóyá a kò ní sùúrù tó ní ìwọ̀n díẹ̀ pẹ̀lú àwọn ẹni tí kò gbé ìgbé ayé tó òṣùwọ̀n tiwa bí? Ṣé a wà lórí atúkọ̀ ara wa, tó nlọ nínú àwọn ìṣípòpadà, tó nlọ sí àwọn ìpàdé, tó ńyán nínú yàrá ẹ̀kọ́ ìhìnrere, àti pé bóyá a nwo fóònù àgbéká wa láárín ìsìn oúnjẹ Olúwa?

Tàbí ṣé a dàbí obìnrin yí, tí ó rò pé òun ti sọnù pátápátá àti pé òun kò nírètí nítorí ẹ̀ṣẹ̀?

Njẹ́ a*ní ìfẹ́ púpọ̀ bí?* ?

Njẹ́ a lóye gbèsè tí a jẹ́ Bàbá Ọ̀run tí a sì nbẹ̀bẹ̀ pẹ̀lú gbogbo ọkàn wa fún oore ọ̀fẹ́ ti Ọlọ́run bí?

Nígbàtí a bá kúnlẹ̀ láti gbàdúrà, njẹ́ èyí jẹ́ láti tún tìtobi jùlọ ti òdodo ara wa sọ, tàbí ó jẹ́ láti jẹ́wọ́ àwọn ẹ̀bi wa, kí a bẹ̀bẹ̀ fún àánú Ọlọ́run, àti sísun ẹkún ìmoore fún ètò àgbàyanu ti ìràpadà bí?[25]

A kò lè ra ìgbàla pẹ̀lú owó ìgbọràn; ẹ̀jẹ̀ Ọmọ Ọlọ́run ni a fi ràá. [26] Rírò pé a lè ṣe pàsípààrọ̀ àwọn iṣẹ́ rere wa fún ìgbàlà dàbí ríra tíkẹ́tì ọkọ̀ òfúrufú tí a sì ńrò pé àwà ní a níle iṣẹ́ ọkọ̀ ọ̀fúrufú náà. Tàbí rírò pé lẹ́hìn sísan owó lílò ilé fún ìbùgbé wa, àwa ní ó di gbogbo orí ilẹ̀ ayé mú nisìsìnyí.

**Nígbànáà kínìdí láti gbọ́ran?**

Bí oore ọ̀fẹ́ bá jẹ́ ẹ̀bùn Ọlọ́run, nígbànáà kíni ìdí tí ìgbọ́ran sí àwọn òfin Ọlọ́run fi ṣe pàtàkì? Kíni ìdí tí a fi nyọnu pẹ̀lú àwọn òfin Ọlọ́run—tàbí ironúpìwàdà, fún ọ̀ràn náà? Kíni ìdí tí a kò fi gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni wá kí a sì jẹ́ kí Ọlọ́run gbà wá là?

Tàbí, láti bi wá ní ìbéèrè náà ní àwọn ọ̀rọ̀ Páùlù, "Njẹ́ a lè wà nínú ẹ̀ṣẹ̀ kí a ní kí oore ọ̀fẹ́ ó máa pọ̀ si?" Ìdáhùn Páùlù rọrùn ó sì dá ṣáká: "Ọlọ́run kò ní jẹ́."[27]

Ẹ̀yin arákùnrin àti arábìnrin mi, à nṣe ìgbọ́ran sí àwọn òfin Ọlọ́run—nítorí ìfẹ́ tí a ní fún Un!

Títiraka láti ní òyé ẹ̀bùn oore ọ̀fẹ́ Ọlọ́run pẹ̀lú gbogbo ọkàn àti inú wa nfún gbogbo wa ní àwọn ìdí láti nífẹ́ àti láti gbọ́ran sí Bàbá wa Ọ̀run pẹ̀lú ọkàn tútù àti ìdúpẹ́, àti pé ó ńdarí wa padà síwájú Rẹ̀. "Ẹ̀mí Olúwa [Ọlọ́run wa]" ńmu ìyípadà ńlá wá sínú ọkàn wa, . . . tí àwa kò sì ní ẹ̀mí láti ṣe ibi mọ́, ṣùgbọ́n láti ṣe rere títílọ" Gẹ́gẹ́bí a ṣe nrìn ní ipa ọ̀nà ti ọmọ ẹ̀hìn, ó ntún wa ṣe, ó nmú wa gbèrú si, ó nràn wá lọ́wọ́ láti dàbíi Rẹ̀, àti pé ó ndarí wa padà sí ọ̀dọ̀ Rẹ̀. "Ẹ̀mí Olúwa [Ọlọ́run wa]" nmu irú "ìyípadà nlá náà wá sínú wa, . . . tí àwa kò sì ní ẹ̀mí láti ṣe ibi mọ́, ṣùgbọ́n láti ṣe rere títílọ"[28]

Nítorínáà, ìgbọ́ran wa sí àwọn òfin Ọlọ́run nwá bíi ìfarahàn ìwà ẹ̀dá ti ìfẹ́ àìlópin wa àti ìmoore fún inúrere Ọlọ́run. Irú ìfẹ́ tòótọ́ àti ìmoore yìí yíò fi tìyanu tìyanu pa àwọn iṣẹ́ wa pọ̀ pẹ̀lú oore ọ̀fẹ́ Ọlọ́run. Ìwàrere yíò ṣe àwọn èrò wa lọ́ṣọ́ láìsimi, tí ìgbẹ́kẹ̀lé wa yíò sì lágbára síi níwájú Ọlọ́run.[29]

Ẹ̀yin arákùnrin àti arábìnrin mi ọ̀wọ́n, gbígbé ìgbé ayé ìhìnrere tòótọ́ kì ṣe àjàgà. Ó jẹ́ ìṣe ayọ̀ ìmúrasílẹ̀ kan—fún jíjogún àpapọ̀ ògo ti gbogbo ayérayé. À nwá láti gbọ́ran sí Bàbá Ọ̀run nítorí àwọn ẹ̀mí wa yíò ṣe déédé pẹ̀lú àwọn ohun ti ẹ̀mí. Àwọn ojú ìworan tí a kò mọ̀ pé ó wà yíò

ṣí. Ìfòyehanni àti òye nwá sọ́dọ̀ wa nígbàtí a bá ṣe ìfẹ́ ti Bàbà.[30]

Oore ọ̀fẹ́ jẹ́ ẹ̀bùn kan ti Ọlọ́run, àti ìfẹ́ wa láti ṣe ìgbọ́ran sí ìkọ̀ọ̀kan lára àwọn òfin Ọlọ́run jẹ́ nínà ọwọ́ ayé ikú wa jáde láti lọ gba ẹ̀bùn mímọ́ yí láti ọ̀dọ̀ Bàbá wa Ọ̀run.

**Gbogbo ohun tí a lè ṣe**

Wòlíì Nífáì ṣe ìrànlọ́wọ́ pàtàkì sí lílóye wa ní ti oore ọ̀fẹ́ Ọlọ́run nígbàtí ó kéde: "À ṣiṣẹ́ láìsinmi . . . láti yí àwọn ọmọ wa lọ́kàn padà, àti àwọn arákùnrin wa pẹ̀lú, láti gbàgbọ́ nínú Krístì, àti láti ṣe ìlàjà pẹ́lú Ọlọ́run; nítorí a mọ̀ pé *nípa oore ọ̀fẹ́ ni a gbà wá là, lẹ́hìn gbogbo ohun tí a lè ṣe*."[31]

Síbẹ̀síbẹ̀, ó máa nyamí lẹ́nu bí a bá fi ìgbà míràn ṣi ìtumọ̀ gbolóhùn ọ̀rọ̀ náà sọ "lẹ́hìn gbogbo ohun tí a lè ṣe." A gbọ́dọ̀ lóye pé "lẹ́hìn" kò bá "nítorí" dọ́gba.

A kò nígbàlà "nítorí" ti gbogbo ohun tí a lè ṣe. Ṣe ẹnikẹ́ni lára wa há ti ṣe *gbogbo* ohun tí a lè ṣe bí? Njẹ́ Ọlọ́run ndúró títí tí a ti ṣe gbogbo ìgbìyànjú wa tán kí Ó tó dá sí ọ̀rọ̀ ìgbé ayé wa pẹ̀lú ìgbàlà oore ọ̀fẹ́ Rẹ̀?

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn ló ti ní ìjákulẹ̀ nítorí wọ́n máa nkùnà léraléra. Wọ́n mọ̀ lọ́wọ́ kan pé "ẹ̀mí nfẹ́ nítòótọ́, ṣùgbọ́n ó ṣàìlera fún ara."[32] Wọ́n gbé ohùn wọn sókè pẹ̀lú Nífáì ní kíkéde pé, "Ọkàn mi kún fún ìbànújẹ́ nítorí àwọn ẹ̀ṣẹ̀ mi."[33]

Mo mọ̀ dájú pé Nífáì mọ̀ pé oore ọ̀fẹ́ Olùgbàlà *yíò fàyè* gbà wá *yíò sì fún wa lágbára* láti borí ẹ̀ṣẹ̀.[34] Èyí ni ìdí tí Nífáì ṣe ṣiṣẹ́ kárakára láti rọ àwọn ọmọ àti arákùnrin rẹ̀ "láti gbàgbọ́ nínú Krístì, kí wọ́n sì bá Ọlọ́run làjà."[35]

Lẹ́hìn gbogbo rẹ̀, *ìyẹn ni* ohun tí a lè ṣe! Àti pé *ìyẹn ni* iṣẹ́ wa ní ayé ikú!

**Oore ọ̀fẹ́ Wà fún gbogbo wa**

Nígbàtí mo ro nkan tí Olùgbàlà ṣe fún wa títí lọ dé Ọjọ́ Ìsinmi Àjíìde ìkínní, mo fẹ́ láti gbé ohùn mi sókè kí nsì kígbe ìyìn sí Ọlọ́run Ọ̀gá Ògo jùlọ àti Ọmọ Rẹ̀, Jésù krístì!

Àwọn ẹnu ọ̀nà ọ̀run ṣí!

Àwọn fèrèsé ọ̀run ti ṣí!

Lóní àti títí láé oore ọ̀fẹ́ Ọlọ́run wà fún gbogbo àwọn tí ó ní ìrora ọkàn àti àwọn tí wọ́n ní ẹ̀mí ìròbìnújẹ́.[36] Jésù Krístì ti palẹ̀ ọ̀nà mọ́ fún wa láti gòkè lọ síbi gíga tí kò lè yé ọkàn àwọn enìyàn.[37]

Mo gbàdúrà pé a ó rí pẹ̀lú ojú tuntun àti ọkàn tuntun pàtàkì ayérayé ti ìrúbọ Ètùtù Olùgbàlà. Mo gbàdúrà pé a ó fi ìfẹ́ wa fún Ọlọ́run àti ìmoore hàn fún ẹ̀bùn àìlópin oore ọ̀fẹ́ Ọlọ́run nípa pípa àwọn òfin Rẹ̀ mọ́ àti fífi tayọ̀tayọ̀ "rín[rìn] nínú ọ̀tun ìgbé ayé [kan]."[38] Ní orúkọ mímọ́ ti Olùkọ́ni àti Olùràrapà wa, Jésù Krístì, àmín.

**ÀWỌN ÀKỌSÍLẸ̀ RÁNPẸ́**

1. Wo 1 Corinthians 15:55; Mosiah 16:8.
2. 1 Peter 1:3; ìtẹnumọ́ àfikún.
3. 1 Thessalonians 4:18; woàwọn ẹsẹ 13–17 bákannáà.
4. Jacob 4:12.
5. 2 Nephi 25:26.
6. Alma 34:10, 15.
7. Ephesians 3:18–19.
8. Doctrine and Covenants 93:28.
9. Nítòótọ́ a jẹ́ "àwọn ọmọ kékeré àti pé . . . síbẹ̀síbẹ̀ a kò tíì lóye bí àwọn ìbùkún tí Bàbá ní ní ọwọ́ Rẹ̀ tí ó sì ti pésé sílẹ̀ [fún wa]" (Doctrine and Covenants 78:17).
10. Romans 3:23.
11. 1 Nephi 15:34; see also 1 Nephi 10:21; Moses 6:57.
12. Mosiah 2:21.
13. Wo Alma 42:15.
14. Alma 34:10, 15.
15. Wo Isaiah 1:18.
16. 1 Nephi 2:6.
17. Wo 2 Peter 1:11.
18. Doctrine and Covenants 76:56.
19. WoDoctrine and Covenants 76:59.
20. WoDoctrine and Covenants 84:38.
21. Mosiah 27:25.
22. Moroni 10:32.
23. Rí Ether 12:27.
24. Rí Luke 7:36–50; àtẹnumọ́ àfikún.
25. Òwe ti Krístì nípa Pharisee àti agbowó òde ṣàlàyé àmì yí kedere (rí Luke 18:9–14).
26. Rí Acts 20:28.
27. Romans 6:1–2.
28. Mosiah 5:2.
29. Doctrine and Covenants 121:45.
30. Ri John 7:17.
31. 2 Nephi 25:23; ìtẹnumọ́ àfikún.
32. Matthew 26:41; wo bákanáà Romans 7:19.
33. 2 Nephi 25:26.
34. Rí 2 Nephi 4:19–35; Alma 34:31.
35. 2 Nephi 25:23.
36. Rí 3 Nephi 9:19–20.
37. Rí 1 Corinthians 2:9.
38. Romans 6:4.

© 2015 láti ọwọ́ Intellectual Reserve, Inc. All rights reserved. Tí a tẹ̀ ní USA. Àṣẹ Gẹ̀ẹ́sì: 6/14 Àṣẹ Ìyírọ̀padà: 6/14 Ìyírọ̀padà ti *Visiting Teaching Message, May 2015*. Yoruba. 12585 779